# IROHIN YORUBA

Esin oro wa—"IWAJU L'OPA EBITI NRE SI"

VOL. IX NO. 440 MONDAY DECEMBER 14 1953 KỌBỌ KAN (1d)

# Adajo Ni Dokita Akanni Doherty Ko Jebi

EKO. Ni ọjọ Iṣegun ti iṣe ọjọ kẹsan oṣu yi ni Adajọ F. O. Lucas ti Kotu Kinni Sant Anna ṣe idajọ ẹjọ ti awọn Ọlọpa mba Dọkita Akanni Doherty ṣe pe o fun awọn janduku enia kan ti nwọn pe si ile Alhaji Olorogun ni owo lati fi ra biriki ti nwọn yio sọ lu Adeyinka Oyekan ati awọn alatilẹhin rẹ nigbati Adeyinka Oyekan ti ilu Oyinbo de ti nwọn si nṣe ere ayọ fun un, ati pe Dọkita na sọ awọn igo ba awọn elere ayọ na ni Idunmagbo Avenue ni iwaju ile rẹ (ile Dọkita na.)

Oloye F.R.A. Williams ni Agbẹjọro Dọkita Akanni Doherty o si fi han Adajọ pe ko si ẹjọ ti Ọlọpa ni lati ba Dọkita na ṣe. Ninu alaye rẹ, o fi han Adajọ na pe ninu awọn ti wọn wa jẹri tako Dokita Akanni Doherty ki iṣe ọmọluabi ati bi ẹri wọn ko ti ṣe dogba rara si, ati pe Agidiagi ọkan ninu awọn ẹlẹri na si ti wọ ẹwọn ri. Ṣugbọn Ọgbẹni Manuel Munas Agbẹjọro Ijọba sọ pe Dọkita Akanni Doherty ni ẹjọ lati ro.

Adajọ na sọ nigbati o nṣe idajọ rẹ pe ẹri eke, ti o pa ni

Wo oju ewe kẹrin

# Akinyele Di Balogun Ibadan

IBADAN- Ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi ni ṣe awọn oṣelu, Oloye ati awọn enia pataki pataki miran ati awọn oriṣiriṣi ẹgbẹ pe ṣọṣọ si ile Ọlọla Igbintade Kinni, Olubadan Ibadan. Olukuluku wọn si ṣe ọṣọ ti o ga lọla. Oriṣiriṣi ilu ndun, ọpọlọpọ awọn alabaṣeyẹ ọjọ na si nla ijo ayọ mọra lati arọ kutukutu titi ilẹ fi ṣu, ero ọjọ na bu aiya, nigbati o ma a fi di agogo mọkanla arọ, ọsẹ gbogbo enia ti pe sibẹ babi, enia fẹrẹ ma a ṣubu le ara wọn lori.

Ni inkan agogo mọkanla ọjọ na ni Oloye I. B. Akinyele ti yio je Balogun, Oloye Salawu Aminu ti yio je Ọtun Balogun, Oloye B. Akinyọ ti yio jẹ oye Osi Balogun ati Oloye Gbọlagun Arulogun ti yio jẹ oye Asipa Balogun ati Oloye Aderinoye Irefin ti yio je Ẹkerin Olubadan de si ile Olubadan fun jijẹ oye wọn na.

Ọlọla Olubadan Ibadan ni o ṣe alakoso apejọ aseyẹ na Oluwo ni o ṣe eto ifijoye na ti o si ja ewe oye le wọn lori, o si fi ọpa oye fun Oloye Balogun Ibadan titun na, bi awọn ti nfi wọn je e si ibọn ndun ti awọn alabaṣeyẹ



DOKITA AKANNI DOHERTY
Nigbati o jade bọ lati inu Kotu

ọjọ na si nyọmbo wọn. Eyẹ ọjọ na dun o lariaria. Irohin ko to amojuba ni. Awọn ijoye na si fi oriṣiriṣi ti, oriṣiriṣi onjẹ adidun ati ọpọlọpọ siga te gbogbo alabaseyẹ ọjọ na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn enia pataki pataki ti o pe si ibi eyẹ na ni awọn Ọlọla ati Iyaafin Ọbafemi Awolọwọ, E.A. Babalola (Minister for Works) S.O. Awokoya (Minister of Education), S.O. Ighodaro (Minister for Health), J.F. Odunjo (Minister for Lands), T.M. Shankland (Civil Secretary) ati Ajẹlẹ Agba Ibadan. Oye a mọri o.

# Ijo Saint Paul Se Ikore

ONITSHA—Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kinni osu ti o kọja yi ni awọn Yoruba Ijọ "Saint Paul Church, Onitsha" se ikore ẹgẹ bi nwọn ti ma a nse e ni ọdọdun. T'Ọkunrin t'obirin wọn fi oriṣiriṣi aṣọ dabira ni ọjọ na ti Ẹgbẹ awọn Iṣe-Ọlọrun-Tan ko se fi ẹnu sọ. Awọn akọrin okorin bi Awoko, nwọn fi oriṣiriṣi orin didun korin ẹhinlẹ lọjọ na. Ọgbẹni O. Ishọla Atọdura wọn ni fi duro dabira, bi orin ati duru ti odun, bẹni awọn Ẹgbẹ Iṣe-Ọlọrun-Tan ṣia ijo mọra. Alufa P. C. Okafor ni o se akanse iwasu ajọdun Ikore na.

Awọn oriṣiriṣi ijọ ni o wa si ibẹ ati awọn enia pataki pataki lati igun mẹrẹrin ilu Onitsha, awọn ti pọju ki a ma a daruko wọn lekọkan 15. Aaiyi aamọdan.

# Sotunde Di Oko Adepate

YOBO LỌNA ABALABI—Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejilelogun osu kọkanla ọdun yi ni Ọgbẹni Z. A. Ṣotunde gbe Omidan Adepatẹ Ọmọ Ilaiye ni iyawo. Irohin ko to amojuba di ... igbeyawo na ti ọkọ-iyawo ṣe.

Ni agogo meje owurọ ọjọ na ni ẹsẹ awọn Ẹgbẹ Oredẹgbẹ ti iṣe Ẹgbẹ ọkọ iyawo ... ile ọkọ-iyawo. Nwọn si ba ... ati iyawo lọ se idupẹ igbeyawo ninu ile ẹsin Ọlọrun "Yoruba African Church." Awọn ... na, lẹhin isin idupẹ ba ... na wa si ile ọkọ-iyawo.

Tiamiyu Onilufaaji wa ... fi ilu dabira, bẹna ni gbogbo awọn alabaseyẹ na si bẹrẹ si jo ijo aseyẹ na pẹlu igbadun ati ayọ. Ọkọ iyawo si fi oriṣiriṣi onjẹ adidun, ipanu, obi ati siga pelu oriṣiriṣi ọti lẹ gbogbo awọn alabaseyẹ na lọrun.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaseyẹ ọjọ na ni Ọgbẹni Johnson Adesanya (Ataba Ẹgbẹ), J. Shorungbe (Olori), J. Ọlọkode Church (Akọwe), E. A. Balogun, S. O. Olutade, S. O. Ọdẹyale, T. A. Ṣẹsan, I. F. Shorungbe, J. B. Akilade, E. L. Ọlọdunjoye, E. Ọlatubọsun, T. Shorungbe, S. Adepọju ati ọpọlọpọ ti ko si aye lati daruko wọn. Ẹhin Iyawo ko ni mọ ẹnẹ ... iwọyi amọdun ọmọ titun.

# Ipade Ajumose Omo Ilu Erin

ONSE-OLOSE, LEBA-OTTA—Ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kinni oju kọkanla ọdun yi ni awọn Ẹgbẹ Ajumọse Ọmọ Ilu Erin ni Oanẹ-Olose bẹrẹ ipade ni dede agogo mọkanla owuro. Awọn Ọgbẹni Abraham Faniyi (Onigbagbọ) ati Salami Onidẹra (Musulumi) ni nwọn fi adura kiku si ipade na, Ọgbẹni Salawu Seriki ni o jẹ alaga.

Pataki ohun ti nwọn sọ ọrọ le lori ni nipa Posu Ọffisi Ilu wọn. Awọn ẹgbẹ na si fi ohn le e pe awọn ti o ba ku ti nwọn o baili sau owo wọn, ki awọn gbiyanju lati san an fun Akapo Ẹgbẹ na. Nwọn nse Ipade na de opin pẹlu adura pataki lati ẹnu Ọgbẹni A.A. Ọlọlade ati Lemọọsu Onẹ-Olose.

Ọpọlọpọ awọn enia ni wọn wa si ibi ipade na lati awọn ilu Eko, Iju-Ọsa, Ayọbọ, Agbado, Aganna, Ọlọsunda ati Ẹdatẹdo.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn bi ọgọrun enia pataki pataki ti nwọn pe si ibẹ ni awọn Ọgbẹni Salami Okeọla, Michael Ajayi, Sanni Ẹrinlẹde, Asani Ọmọmeji, Salami Ladọsu, Osani Olaniyan, D.A. Awoniyi, Salaku Alabi ati Alfa Mọmọ Mọgida.

Ki Oluwa mu ẹsẹ Ẹgbẹ na duro.

REDIFFUSION

FOR LESS THAN THREEPENCE PER DAY
you can obtain
NEWS
MUSIC
EDUCATION
ENTERTAINMENT
FROM 6 A.M. TO 11 P.M.
IN YOUR OWN HOME
APPLY AT OFFICES IN LAGOS, IBADAN & ILESHA.

